**Akiyesi**

Anfẹ Enti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbogbe Ilọrintabi Ilumiran. E kowe si odọ Ọgbeni: R. O. Adedeji Esq Ni P. O. Box 12 Ilọrin

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**AKIYESI**

E ma polowo ọja yin sinu Irohin Imole

VOL. III No. 139 MONDAY FEBRUARY 29 — MARCH 6 1960 KỌBỌ KAN (1d)


# Ijoba ti gbe iwe asepari lori oro Ijiroro nipa owo awon

IWE ASEPARI TI IJIRORO LORI ORỌ OWO AWỌN OSIṢẸ TI IJỌBA APAPỌ ATI AWỌN IJỌBA IPINLẸ ARIWA, ILA ORUN ATI SOUTHERN-CAMEROONS YAN TI JADE, IJỌBA APAPỌ ATI AWỌN IJỌBA IPINLẸ DE TI GBA OWO ẸKUNWO TI IGBIMỌ IJIRORO NA TI ỌGBẸNI L. N. MBANEFO ṢE.

(Artisan Grade 111) Sile mẹjọ kọbọ mẹjọ pẹlu ẹkunwo kọbọ meje lọdọdun. Awọn ti o wa ni ipo keji (Grade 11 Sile mejila kọbọ kan lojọ pẹlu ẹkunwo kọbọ meje lọdodun, awọn ti a wa ni ipo kini (Artisan Grade 1) Sile mẹrindilogun kọbọ meji lojọ pẹlu ẹkunwo sisi lọdọdun.

Aye ko si lati kọ ti awọn akowe ati awọn osiṣẹ imiran, ṣugbọn a gbọ wipe ipari osu yi ni wọn yio san a

# osise ti Ogbeni L.N. Mbanefo

tẹhin wa ẹkun wo na.

(ARREAS MARCH ENDING)

Ninn iwe iṣẹ pari won Igbimọ Mbanafo sọ wipe ki Ijọba ṣe iwadi imiran nipa nwo onjẹ ati ọja atipe awọn lero wipe gbogbo Ijọba Naijiria yio jijọ gbimọ pọ lati ri wipe awọn nsan iye owo kanna fun gbogbo oṣiṣẹ jakejado Naijiria. Wọn tun sọ wipe ki Igbimọ nipa owo osiṣẹ ni Ipinlẹ Ariwa pe ki wọn ṣe ipade lati se ifikun owo siwaju si i fun awọn oṣiṣẹ Ipinlẹ na, nitori owo wọn lo kere ju ni ilẹ Naijiria. Nisinyi awọn Alaru ati oṣiṣe Ipinlẹ na ni a fi kọbọ mẹsan kun owo wọn.

Ninu Iwe kan ti Alaṣẹ eto Iṣẹ Ijọba Mallam Musa Yar Adua gbe tẹle jade iwe ipari ijiroro na o sọ wipe "Nitori pe owo nkan nkan ọja ati onjẹ ngasi lojojumọ.

Ijọba Apapọ ni lati ri i pe owo ti a ngba ni ibi iṣẹ gbọdọ tẹ awọn Osiṣẹ lọrun, ti wọn ko li ni rasa, ki wọn ba le lowo lọwọ lati fi ra ani ni pataki onjẹ jijẹ, gẹgẹbi ọrọ Gorsuch ti Ijọba gba. Ninu ipinnu yi Ijọba fẹ fi yeni wipe ki iṣe pe a gbe ipo Osiṣẹ ga ra ra bikoṣe-

# jade, won si gba Ekunwo ti

pe ijọba ṣe ayẹwo owo Oṣiṣẹ wọn dẹ ṣe afikun, eyi yi ni ni pe kiṣe pe agbe awọn Oṣiṣẹ si iwaju ju ipo tiwọn wa nisisiyi lọ bikoṣepe a fi owo kun owo wọn Ijọba tun sọ wipe lẹhin ti a ti yan Igbimọ ijiroro yi a ṣe afikun le-lẹmẹwa owo awọn Osiṣe ki o to di wipe Igbimọ jiroro owo Oṣiṣẹ ti Ọgbẹni Mbanefo to bẹrẹ iṣẹ tirẹ. Ijọba ni ohun ti o fa ti awọn ṣeṣe ifikun ida-mẹwa yi ni lati ma jẹ ki awọn Oṣiṣẹ damu nipa owo nina.

Ijọba wa ṣe ikede pe lati oṣu Decamber ni iwe aṣe pari ti Igbimọ Ijiroro lo ri ọrọ owo awọn oṣiṣẹ na ti tẹ awọn lọwọ, ṣugbọn awọn duro gba imọran lọwọ awọn ẹgbẹ osiṣẹ ati awọn Ijọba Ipinlẹ ki awọn to tẹ ẹ jade Imọran ati isọsi ti awọn gba yl ti ṣe iranwọ fun awọn, awọn dẹ ti ka a keye.

Mallam Musa Yar Adua wa pari ọrọ rẹ nipa sisọ wipe Ijọba Apapọ gba gbogbo ọrọ ti o wa ninu iwe iṣe pari ti igbimọ Ọgbẹni Mbanefo yi ati papa pe ki owo titun ti a o ma san yi bẹrẹ lati ọjọ kini oṣu kẹsan ọdun tokọja (1st September 1959).

Nisinyi awọn osiṣẹ ti alaru (Labourer) yio ma gba sile marun kọbọ mẹwa lojọ, a o dẹ ma fi kọbọkọbọ kun owo wọn lọdọdun, awọn oniṣẹ ọwọ ti wọn wa ni ipo kẹta

# Igbimo na se


## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpolọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi jẹdi Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọrun fun awọn ọmọde, osi njẹki awọn ọmọde lobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Ara yin leti pa MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti koṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

LILO RE:- Jibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 204247

# Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata todaraju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹrilọ lẹyin ata lilọ o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba ati Ẹwa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nta** Pẹlu Enjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Ẹlẹtiriki Mutọ.

O WA NI SỌBU:-

**Akoshile Brothers,**
5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.



## ITUMO Ala awon Onibere

IPIN AIṢẸ ỌMỌ Ọ'TUN ORO LAGOS-

Iwọ ọrẹ mi maṣe ba ẹnikẹni da nkan owo pọ lasiko yi ki wọn ma ba gbe ọ ni agbeda. Tun ṣọra lasiko ki ọrẹ rẹ timọtimọ ma ba fi Ọbẹ ẹhin jẹ ọ ni isu.

Bere ala tirẹ na lọwọ JOSEPH ALALA
6, Ojo Road, Odauborẹ MUSHIN.


# Petepete T'ana Ni Popa.

EKU ARỌ O. Ẹnyin ara, kini ẹti nse ọrọ ti awẹ yi si o? Nitoripe Pẹtẹpẹtẹ tana ni popa ko gburo kọkẹkẹ kankan nitoripe ebi kise on to se fi se ọrẹ.

Asitu li lai, Alla ni ki ọdakẹ? Salamalekun jọnmọ? ẹniti oba ka iwe mi ninu Irohin Imọlẹ ọdun to kọja nipa ọrọ awọn Onimọle ti mo kọ sibẹ, oluwarẹ yio ri wipe nko purọ rara.

Ẹnyin Ọkawe Irohin Imọlẹ yio ri wipe gbogbo adugbo ni yio di Mọṣaasi lẹnu ọjọ mẹta yi. Iwọ Onimale eke, ewo lẹse o? se o ma gba awẹ ọdun yi dada, a bi bi o ti se gba ti ọdun to kọja na ni o tun ma gba ti ọdun yi jọwọ bi o ba lọ kirun ko mase jẹki omi diẹ bọ si enu rẹ o Nitoripe mo ti mọ wipe iwọ ko fẹ gba awẹ ọdun ni. Iwọ Alagabagebe njẹ oti da ọgbọn ti o ma nda lọdọdun? Njẹ emọ iru ọgbọn ti awọn Onimale na ma nda? o ti o Se ẹri? bi oba ti di asiko awẹ gbigba? ọrẹ wa a lọ si ọdọ Dọkita, a ni ki o fun on ni abẹrẹ (Injection) nitorina a ma fi iyẹn parọ kakiri pe' mo gun abẹrẹ ni hosipitu loni, Dokita ni nko gbodọ gba awẹ rara fun osu kan! sẹ alakọri ti mọ pe osu kan na ni awẹ gbigba npari.

Awọn mirau a sọpe ẹniti ko gbọn ni awẹ ngbo! ẸkỌ meji ko ba awẹ jẹ Sugbọn ti o ba di asiko ọdun gbogbo olukuluku awọn onimale yio ko ilu jade wọn a ma jo ijo kakiri, ati ẹniti o gba awẹ ati ẹniti ko gba awẹ gbogbo wọn a ma da oju titi ru kakiri Iwọ alufa buruku O ya lọ gbe kurani rẹ jade nibiti o ti gbe ju si lati ọdun to kọja, ko ma gba kọbọkọbọ Kakiri, bi o ti gba lọdun to kọja Enkan lọdun ni alakọri ara rẹ nse wasi tirẹ gbogbo ọrọ na sa ni mo le pe ni: Bo kirun bo kirun nso ni mọsa-lasi, bo gba awẹ, bo gba awẹ nso ni yidi ni ọjọ ọdun Ewo lo se iwọ ni mo nbawi ọba tete fun mi lesi kingbọ Alufa, toripe ma sọ kisa siyin lara Ebi npami awẹ ngbomi, ẹpe Lemọmu kope irun. Eyin onkawe, mo bẹyin kẹ mase sun mọ awọn alawẹ na ni ọsa rara o, nitoripe ebi ti fẹrẹ yọ wọ loju bi ẹbi si lọ tọ wọn, wọn yio fi ikanra awẹ mọ yin Bi o ba de ebute Moloni bridge Street, wa mọ ohun ti mo npe ni awẹ.


# Yan ọrẹ kan!

siga **GALLEON**

TI NAIJIRIA NFẸ Ṣ'ALEJO




o ndun bi olowo-nla
... owo rẹ si kere pupọ
kọbọ kan fun
ẹyọ kan
**1'8 fun 20**



# MA FI OWURO S'ERE APA 6

Lati Owo: J. O. SHOYINKA (Mushin)

OJU NWỌN RI MABO NINU ỌGBUN

OHUN TI OJU NWỌN RI ninu ọgbun ko ṣe fenu sọ. Akọkọ ti nwọn kọkọ de inu ọgbun, nwọn jẹ onjẹ ajẹ-tagiri ni ipa, ọkan nwọn wa bale bi ọkan Tolotolo. Nigbati o ya ni Omiran tun pada de, o doju kọ Onibode Ọgbun na, o ni ewo lewo? O si dalohun pe dada ni. Lọgan o ti ṣẹju si Onibode, ohun ti o nwi si ye e.

Lọgan ni o parẹ tan, ti Onibode fi bẹrẹsi ba Mafaro Ṣere ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ sọrọ, o ni nko ni purọ tan yin jẹ, nihin ni ẹmi nyin yio ṣegbe si, nitoripe ẹnyin funrara nyin ni ẹ mọ mọ wọle tọ iku wa, jẹjẹ ni o joko si ibugbe ẹ ki ẹ to wa bami ni Alejo, yio si ṣe alejo doju rẹ loni, ti o ba tilẹ jẹ pe iku yio tete fara-ban nyin ni iba dara pupọ ba! iya tiẹ o jẹ ki ẹ to ku nkọ ? Ọdun jọjọ ni ẹ o fi ṣe igbekun nhin ki ọwọ iku to wa tẹ nyin.

Mafarọsere koi ti jẹki o sọrọ rẹ dele ti o fi bẹrẹsi fun akọ esi, o ni, ibẹru kan ko si, ifoiya ati ipaiya ti dopin. dígbì ni a wa bi iku bade, ati mura dee, bi iya papa ba de ati wa bi ẹwa.

Bi a kotilẹ faramọ iku ti a ko si faramọ iya, ọna wo lati lẹ le gba fi sa asala fun ẹmi wa tẹlẹtẹlẹ. Oluwa Alanu lo le mu wa la ewu yi ja.

Onibode ki ṣe pe mo n ṣe gannatan tabi pe mo ndugunla si ọrọ rẹ, ti ọrọ ba di tan ki a ta ni E-epinni. Iwaju ko se lọ, ẹhin ko si ṣe pada si. Kini o tun lọ ki nwi.?

ONIBODE DALOHUN

Onibode ni Mafarọ Ṣere o ti sọrọ tan, aroye lo tun ku, o ti sọ pe ohunkohun ti o ba de o ti faramọ. nje ki a ma ba ere aniyan bọ o, ẹnyin ọrẹ mi.

Bi Onibode ti ngba ilẹ pẹẹpẹrẹ ti o si npe ayajọ kikan-kikan bẹni ẹgun oṣuṣu, dangunro ati ẹkan bẹrẹ si yọ jade lati inu ilẹ wa.

Bi ẹgun yi ti su yọ wi tan bẹni Onibode papa parẹ, atijoko diṣẹ, ati naro dọran, iloṣo papa di inira, ẹgun ti gun nwon lara ṣakaṣaka, ọrọ na wa kuro ni yẹyẹ, awọn ọmọkunrin barajẹ. Mafarọ Ṣere papa ti o ti nṣe akọ barajẹ, omije bẹrẹsi bọ poroporo loju rẹ, se ẹnyin papa mọ ni ọjọ inira ni ẹda mamọ Ọlọrun, nwọn bẹrẹsi ke si Oluwa pe ki o yọ nwon ninu Oro nlanla yi, nigbati Oro mu nwọn tan, nṣe ni olukuluku wo lulẹ wogira eyiti o doju de ẹgun doju de e, eyiti o dehin le ẹgun dehin de e, eyiti o fi ẹbati le ẹgun fi le e, Onibode rọra sa si kọrọ kan, o nwo nwọn.

nigbati o ri wipe nwọn jẹ aporo tẹrun, o ṣebi oro ti pa nwọn ni, o rọra nfi igogori ẹsẹ tẹlẹ bọ wa si ọdọ nwọn. Lọgan ni Mafarọ Ṣere gberi soke, o ni alagba o dakun nitori Ọlọrun gba wa. Tete ba wa ranṣẹ si iku ki o tete wa pa wa.

Onibode ni ẹni suru diẹ si i, ẹ ma mi, ki ẹ si ma fi igbadun s'ayọ mo nlọ pe Iku wa o.

Akiyesi :— Lọsẹ to nbọ ẹ o ma ka apa (7) ati bi nwọn ti nfi ẹmu gbigbona yọ ẹgun lara nwọn.

### Ohun ti Irawo nyin wi

Jan 21- Feb 19: Awọn ti o jẹ ọga rẹ yio gba ọ tabi ohun ti o ba nṣe tayọtayọ

Feb 20 Mar 20 Irinajo tabi ọrọ aya tọkọ ni tirẹ lọsẹ yi

MAR 21- APr 22. Ipọnle lati ibi ti o ko lero

April 21- May 22. Iyatọ si rere ninu ohun ti onṣe.

May 22- Jun 21 wa ọna titun ninu ohun rẹ

June 22- July 22, Nkan kan ṣẹlẹ ti yio gba ọ lọkan

July 23- Aug 22 Asiko atata fun owo tabua

Aug 23- Sept 22 wa nkan ti inu rẹ nfẹ gidi.

Sept 23- Oct wa ri ere ti o ṣiṣẹ rẹ je.

oct 23- Nov 21- wa ba ẹni abami pade Nov 22-Dec 22 wa wo ẹgbẹ titun wa si ni ọrẹ titun. Dec 23- Jan 20. wa ri iwe ayọ gba.

Printedand Published by MODUPE PRINTING PRESS
16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21985.
Oluu: E. A. Adeniji No. 31, Tejuosho Street Suru-lere. Yaba
FUN OWO "IROHIN IMOLẸ" ỌDUN KAN EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mẹfa ati-Kọbọ Mẹfa (6/6d)


## MA SO IRETI NU RARA O

Bere awọn ojulowo egbogi Jamani ati orisirisi ilu miran wọnyi pataki ni fun 'AJO' tabi 'ITỌJU' Obinrin tabi Ọkunrin, ti ọkọ ati iyawo ti o daju, Meji iru wọn ko si ni gbogbo sọbu ni igboro ilu Eko.



Ekini:- Egbogi ti a npe ni ERMELINDA fun Obinrin orisi mẹta lo wa ninu Pali rẹ, o pa bambari fun ajo tabi idiwọ Adọta ṣile (50/-) ni owo pali kan jẹ, owo ọkọ 3/6

Ekeji:- Egbogi ti a npe ni SANURSEX fun Obinrin Ṣilemejilelọgbọn pẹlu sisi (32/6d) owo ọkọ 2/6

Ẹkẹta:- Egbogi ti npe ni OPO-JUVEN fun Obirin. (ojulowo Egbogi Awọn Faranse) Ṣilmejidinlogun abọ 18/6 owo ọkọ 3/6

Ẹkẹrin:- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN fun obinrin Ṣilemerinla abọ (14/6 owo ọkọ 2/-

Ẹkarun:- Egbogi ti a npe ni FANDORINE fun obinrin (Egbogi Faranse) Ṣilemerila-abọ (14/6) owo ọkọ 2/-

Ẹkẹfa:- Egbogi ti a npe ni OSTORPIROS fun obinrin Ṣilemejo-abọ (8/6) owo ọkọ silekan pere (1/-)

### Ojulowo Egbogi fun Ajo Ilera ti Okunrin

Ekini:- Egbogi ti a npe ni SANURSEX
Ọgbọn ṣile (30/-) Igo nla Owo ọkọ 3/-
Ekeji:- Egbogi ti a npe ni TESTONIC
Pọwun-kan (£1) igo kerere mewa-abọ owo ọkọ 2/-
Ẹkẹta:- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN
Ṣilemejila-abọ (12/6) owo ọkọ 2/-

Awọn egbogi wọnyi lagbara gidigidi wọn si nṣiṣẹ ribiribi fun awọn ti wọn nlo wọn ẹlu wọn ko dabi awọn egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro iṣẹ wọn yatọ patapata, o si daju pẹlu.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orisirisi amodi ti o ba fe ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palm Church Street. P. O. Box 333
Lagos Nigeria Phone 22878
Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-
MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE IBADAN
ati ni ABIMBỌLA MEDICINE STORES
B29 Okesha Street, Ilesha
BISALE MEDICINE STORES
BRITISH & FOREIGN MEDICINE (DEALER)
S W 6/456 AGBOKOJO STREET, IBADAN, N.

KIYESI:— Ri daju gbangba wipe ṣọbu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn elomiran yio fi ERU lọta adamọdi tabi orisi omiran fun o o, maṣe gba rara.